# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VLO XIV NO 899 LAGOS SATURDAY DEC. 14 — DECEMBER 20 1963 KỌBỌ MEJI (2D)


Jamba Sole!

# Ijangbon Be Sile Larin Awon Oselu Wa Lori Ise Biney

EKO—Ijamba solẹ, onile taji ! Ijamba nla kan ti bẹ silẹ larin awọn oṣelu wa tiṣe ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ (N C N C) lori ọrọ iṣẹ ebute ti Ologbe W. Biney ti ngba ogunlọgọ awọn lebira si ni Apapa ati Eko lati ọjọmọjọ, ti awọn Ijọba ni awọn fẹ gbe fun awọn alarobọ kan, awọn si ni lati da ọpọlọpọ awọn lebira ti nwọn gba sẹnu iṣẹ na ni ebute Pọta (Port-Harcourt) ati Apapa duro.

Nigbati ọrọ na kọ bẹ silẹ ere ni, awada ni, ni a pee ṣugbọn lati ọsan ana wa o ti dabi ẹni wipe aiperi fẹ wọ ọrọ awọn oṣelu ọmọ ẹgbẹ Alakukọ kanna yi.

Gẹgẹbi irohin ti Ayiluka "Eleti-Ọfẹ" fun wa lori ọrọ na, o ni nitotọ ni Ijọba ti mura tan lati da awọn lebira Biney silẹ lebute Eko ati ni Pọta ṣugbọn nigbati awọn Ibo kan dide si i ni Pọta, nwọn ni ki nwọn ma da awọn lebira na duro mọ.

Idi eleyi ni o jẹki Ọgbẹni TOS Benson paapa dide si l'Eko. O ni ki Ọgbẹni Njoku, minista alamojuto iṣẹ ọkọ ati ebute ki o ro ọrọ na ṣe fun awọn lebira Apapa nitoripe n'kan ti nwọn ba fi le fa iwe awọn lebira Pọta ya, o yẹ ki awọn le ṣe ti Apapa na pẹlu.

Onirohin wa ni lati ọjọ ti o ti sọrọ na ni awọn apa kan ninu awọn Ibo ti nwọn wa l'Eko ni ki Ọgbẹni Benson fo, ko niṣo. Nwọn ni ko ni ẹtọ lati sọ ọrọ bẹ, nwọn ni o ti pẹ ti awọn ti nsọ ọ bi o ti nfi ọbẹ ẹhin jẹ awọn lẹsẹ lọdọ Ọlọla Tafawa Balewa tiṣe Olotu Ijọba Apapọṣe. Ọrọ na ti tanka ọdọ awọn ọmọ Yoruba ti nwọn wa ninu ẹgbẹ Alakuko ni Ibadan ati Abẹokuta. Nwọn ni bi ẹgbẹ ko ba ṣe ṣe mọ awọn a kuro nibẹ. Nwọn ni ki awọn Ibo ye ko iyan awọn Yoruba kere ninu ọrọ oṣelu.

## OKU KAN JINDE NINU POSI RE

LONDON—Oku ọdọmọdebinrin kan Elsie Waring, ẹni ọdun marundinlogoji ti ti ku ninu ile awọn alaisan kan ni itu Oyi bo ni a gbọ wipe o tun bẹrẹsi mi lẹnin wakati gbọrọ ti nwọn ti gbe e ju sinu posi na lati lọ sin ninu itẹ.

(Wo iyoku ni oju ewe Kẹfa)

Oro Behin Yo!

# Nwon Fe Bu Owo Si Oko Reluwe Laipeyi

EKO — Awọn agbalagba Yoruba ni bi ina ko ba tan laṣọ ẹjẹ ki tan ni eekan ni ọrọ iwadi ifowo kun owo awọn oṣiṣẹ ti Ijọba Apapọṣe ni ki Adajọ Morgan ṣe iwadi. Ọrọ kan ti o jẹ pataki ọrọ ti o bọ lẹnu ọkan ninu awọn ọga ile iṣẹ awọn Reluwe Ọlọkọ-ilẹ na.

Orukọ ọga ile iṣẹ reluwe na ni Ọgbẹni J.C Egbuna, lati ẹnu rẹ ni ọrọ na ti jade nigbati o nsọrọ niwaju awọn Oluwadi ni irọlẹ ijẹta ni Ọdan l'Eko, Ọgbẹni Egbuna tiṣe ọga-agba fun gbogbo awọn oṣiṣẹ reluwe ni Oke-Ira ni Ebute Metta ni ko si ọna ti awọn fi le ri owo fi kun owo awọn oṣiṣẹ yi ju ki awọn ti kun owo ti awọn ero fi nwọkọ jake jado lọ.

Ọgbẹni Egbuna tun se alaye fun awọn oluwadi na wipe ibi iṣẹ awọn ni gbase lọrun pupọ, o ni gbogbo ọna reluwe tuntun ti awọn ṣẹṣẹ si ni Oke Ọya lati idalẹ Oke Okun ni awọn ti ya owo ti awọn lo na Awọn ko si ti san awọn owo na rara.

Awọn oluwadi ni ṣugbọn iye kanna ni owo Egbuna pẹlu Ọlọla Tafawa Balewa ni oṣoṣu, nwọn ni kini faa ti o fi ri ... Egbuna alara ni ... ko ie ṣe alaye idi rẹ ti owo oṣu on ṣe pọju ti awọn ọga-agba ile iṣẹ ẹgbọjọda miran lọ.

Awọn oluwadi na tun bi lere wipe kilọṣe ti awọn Ọlọkọ reluwe ko fi din owo oṣu gọboyi ti nwọn nsan fun awọn akọwe kan ti nwọn npe ni Ọga-agba (Senior post) ku ki nwọn ti owo fi kun owo ti awọn oṣiṣẹ ni awọn fẹ gba yi. Egbuna ni awọn nro ọna ti awọn fẹ gbe ọrọ na gba.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

**Lati Owo Ayiluka**

## Adajo Ghana Gba 'Daduro

Ẹnyin ara mi, ọrọ bẹhin yọ ni irọlẹ Ọjọ ni 'Ru ilu Ghana nigbati ẹniti awọn Aganyin fi ṣe Olotu alakoso ilu wọn, Dokita Kwami Nkrumah gbejo fun olori awọn adajọ-agba 'kotu Ijọba ilu Ghana, Ọlọla (Sir) Arku Korsah lori (boya bẹni, on alara paapa ko le sọ) ẹjọ awọn kan ti nwọn ni nwọn fi igba kan ditẹ lati pa Dokita Nkrumah.

Mo gbọ wipe idajọ ti olori adajọ-agba na ṣe ti o da awọn mẹta kan silẹ ko tẹ ẹ lọrun rara. Mo gbọ wipe lati'ọjọ ti nwọn ti ṣe idajọ na ni Dokita Nkrumah pẹlu awọn ọmọlẹhin rẹ ati awọn ẹgbẹ oṣelu CPP ti nku sile, ti nwọn nku si ita; SIBẸSIBẸ NWỌN GBE IJO fun Ọlọla Arku Korsah ti o nṣe alaga awọn adajọ agba mẹtẹta ti nwọn gbọ ẹjọ na duro ni.

### Lori Ejo T'o Da

Ẹnyin ọkawe mi, awọn enia meji ni mo nọ bi ẹniti o mọ'wo ninu awọn adajọ-agba ti o da ẹjọ awọn ti nwọn pe ni ọlọtẹ yi. Mo mọ Ọlọla Arku Korsah, olori gbogbo awọn adajọ ti nwọn daduro yi; mo tun mọ Adajọ-agba Akufo Addo. Ko nṣe wipe mo mọ wọn nikan, a jọ jẹun pọ lori tabili kamda kiṣe ẹmẹrin mọ. Igbakugba ni mo si ti fi wọ mọto-ayọkẹlẹ awọn mejeji nigbati mo wa ni Gold Coast (ti ẹ npe ni Ghana nisisiyi).

Mo mọ iyawo alarede awọn mejeji, mo si mọ ile ti nwọn ngbe. Adajọ Akufo Addo ni o mu mi mọ Ọlọla Korsah. Ọlọla Korsah jẹ ọkan ninu awọn enia dudu ti nwọn yan lati wa idi bi-o ba yẹ ki nwọn kọ ile ẹkọ-giga (Higher education in West Africa) fun Iwọ Orun Afirika ti nWọn npe ni ELLIOTT COMMISSION nigba na.

### Awon Egba Mo'we?

Lọjọ ti a kọ pade, ọrọ awọn Ẹgba ni Abẹokuta mọ iwe pupọ ni Ọlọla Korsah kọ ba mi sọ, o si tun bere alafia OLOGBE ALUFA I O RANSOME-KUTI "DAWODU", Olori ilewe-giga ni Abẹokuta lọwọ mi. O ni on pẹlu 'DAWODU' ni awọn jọṣe iṣẹ ọna ile ẹkọ giga (University) ilẹ awa enia-dudu. O ni ṣaṣa nibiti on ko gbe de ni igberiko awọn Ẹgba nigbati awọn nṣe iṣẹ nla na; Ọlọla Korsah ni on gbe idi fun awọn ẸGBA ỌMỌ LIṢABI, nwọn gbọ iwe pupọ.

### Nana Oloye

Adajọ Akufo Addo kiṣe lọya kekere larin awọn Aganyi ki o to di adajọ. Lọya Oloye ilu mi, Ladipọ Moore ni o mu mi mọ ọ, Bi Oloye Ladi Moore ti jẹ amofin pataki ni ilẹ Nigeria ni on alara paapa jẹ ni ilu Aganyin, ọmọ oye ni Akufo Addo, bikobasi kikọ ti o ti nkọ oye idile wọn ni, nwọn ko ba ti fi jẹ NANA Akufo ADDO.

(Wo iyoku loju ewe Kẹje

# Iwe Si Olotu

## Se Nwon Ni Osunwon?

Ẹ jọwọ ẹ la ọrọ awọn ẹgbẹ tuntun, awọn Nigeria Association of Medical Herbalists ti ẹ ni nwọn ṣẹṣẹ da ile iwosan nla kan silẹ ni Ita Faji l'Eko ti nwọn nwo awọn alaisan san ti ẹ sọ wipe leto leto ni awọn nṣe nkan wọn.

Ẹ jọwọ ẹ mọ wipe mo ṣe afojudi fun ibere ti mo fẹ bere yi. Ẹ jọwọ ṣe awọn onişegun na ni osuwọn ti nwọn fi nwọn awọn egbogi fun awọn alaisan ti nwọn nwo?

Ibere keji: Ṣe nwọn ni iwe akọsilẹ (record) lati mọ iru awọn enia ti nwọn nwa sọdọ wọn ati iru egbogi ti nwọn nlo fun wọn?

Emi ni,
EKO L. Towolabi

ALAYE OLOTU: Awa ran awọn OLOFINTOTO Eleti-Ofẹ lọ sibẹ, o sọ fun wa wipe tiwọn tiwọn ni awọn onişegun na nwọn egbogi ti nwọn nfun awọn alaisan ti nwọn ntọju. O tun ṣe alaye wipe ko si ẹniti yio de ibẹ ti ko ni gba pali (card) ki nwọn to fun un logun.

AKIYESI: Ẹ jọwọ, ẹ kiyesi ikede pataki yi. Ẹnikẹni ti o ba nkọwe si Olotu ki o ma kọ yanju, ki o si ma foruko rẹ si i pẹlu alaye ọrọ ti o nkọwe le lori. Ọgbẹni S. Aroworowọn, a ri iwe rẹ gba, ọrọ yin ko ye wa rara.

—OLOTU



# Awon Oselu Kan Gbojo Iku Nilu Ghana

ACCRA—Nwọn ṣe idajọ awọn oṣelu marun'ara Ghana ti nwọn ninwọn fi igba kan dite si Ijọba, nwọn fẹ pa Balẹ ilu wọn, Dokita Kwami Nkurumah. Orukọ awọn oṣelu marun na ni Ọgbẹni Ako Adjei, minisita alamojuto ọrọ awọn ilu okere, Ọgbẹni Tawiafi Adar afio, minisita alamojuto ikede ijọba, gbogbo awọn mejeji ti a darukọ yi ni awon adajọ fi silẹ wipe nwọn ko jẹbi rara pẹlu akọwe ẹgbẹ CPP. Ọgbẹni H H Cofie -Crabbe.

Awọn meji ti nwọn dajọ iku fun ni Ọgbẹni Robert Benjamin Otchere ọkan ninu awọn alatako ninu ile igbimọ aṣofin Ghana pẹlu Ọgbẹni Yaw Manu, akọwe ile-iṣẹ Ijọba.

Oṣu mẹrin gbako ni nwọn fi ro ẹjọ na gbako kotu kan pataki ti nwọn da silẹ nitori ọrọ na. Gbogbo awọn ti nwọn wa ni ki wọn pa lori ọrọ nwọn fẹ pa Nkrumah di enia meje nisisiyi.

# Baba Ogboju Ode Pade Agbako Iku Moto

## Baba Ogboju Ode Pade Agboko Iku Moto

BIDA—Anu ṣe ni lati tufọ Oloye D O Fagunwa ti o kọ iwe Ogboju Ọdẹ Ninu Igbo Irunmalẹ ati awọn iwe miran ni ede Yoruba fun lilo awọn ọmọ ilewe, ti o ku ninu ijamba mọto ti o pade lọna Bida nigbati o nrin irin ajo bọ pada si Ibadan. Ẹni ọgọta ọdun ni.

Irohin ti a gbọ nipa ijaba mọto na ni wipe awọn mẹta ni nwọn na ninu mọto pẹlu dẹrẹba ti nwa, a gbọ wipe inu odo kan leti Kabba ni nwọn jasi ki Ọgbẹni na to di ẹni ọrun.

Aṣoju awọn Oyinbo atẹwe kan ni Ologbe na nṣe ni ilẹ yi ki o to pade agako iku yi; nwọn ti gbe oku rẹ lọ si Oke-Igb tiṣe ilu rẹ ni agbegbe Ondo lati lọ sin in.

## Princess Anne Becomes Pupil Of Benende School



Prince Anne, who celebrate her 13th birthday on August 15th will go to Benenden School in Kent, England. She thus follows the new Royal pattern set by her brother Prince Charles he Prince Wales, who is now at Gordonstoun School in Scotland. Previously, all children of the British Royal Family have been educated privately.

Benenden School stands in 200 acres of parkland near Cranbrook in the Weald of Kent. With some 300 pupils, it is divided into six houses; Princess Anne will join Guildeford House as one of 20 girls in the lower fifth form. As a new girl, she will sleep in a dormitory accommodation up to eight girls rise at 7 a.m., make her own bed, take her turn at laying the tables for evening meal; and at week-ends she may be called on to help with the washing up occasionally.

Picture shows: Miss Elizabeth Clarke, headmistress (fourth from right) and Miss Cynthia Gee, [illegible] housemistress (fourth from left), walking with some of the pupils in the ground of B...... School.

# Ijobi Din Owo Bode Lori Panu

EKO — Awọn alamojuto eto inawo Ijọba Apapọṣe l'Eko ti ṣe ikede fun gbogbo awọn onişowo ti o mbẹ nilẹ yi jake jado wipe awọn ti din owo-bode ti awọn yio ma gba lori awọn panu ayẹ ti nwọn ko wọlu.

Nwọn tun ṣe alaye wipe nkan ti o jẹki awọn din owo-bode ku lori awọn panu-ayọ na ni wipe nkan rere ti nfi wọn ṣe pọ pupọ ju fun awọn ara ilu.

Nwọn tun dinwo lori awọn apo ti nwọn fi ndi nkan orişirişi lọ silu okere. Nwọn tilẹ pa owo-bode rẹ lori awọn aṣọ peupepenpe ti nwọn nlo nile iwosan.

Gbogbo afikun ti nwọn ti fi kun owo-bode lati bi ọdun marun wa ni nwọn ṣe atunṣeọrẹ patapata.

# ELETI-OFE

(ANJU WỌN KOSE WI LẸỌ )

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMS

28, Kosọkọ Street, Lagos, P. O. Box 467 "ELETI-ỌFẸ" LAGOS Phone 23370

VOL XIV. NO 899 SATURDAY Dec 14. - Dec 20, 1963.


## ORO OLOTU:

# Awon Aferu Gba Ibukun......

Lati bi ọjọ mẹta ni ariwo ti ngba ile ti okiki ngba adugbo kakiri Ipinlẹ Ariwa, Ipinlẹ Ila Orun ati Iwọ Orun lori awọn asiwaju oṣelu wa kan ti nwọn ngba owo-ẹhin kiri, ti nwọn kọ jẹki ilu wa ni ilọsiwaju.

Awọn Yoruba ni a nje ekuru ki o tan ninu awo nibẹ ni awọn kan tun ngbọn ọwọ rẹ sawo ni ọ r ọ awọn ọmọ akẹkọ ile Nigeria wa ti nwọn ko fe ṣe wahala, ki nwọn kọ ẹkọ akọyege, afi bi nwọn nse bi ole, bi ole gba ibukun wipe awọn ti mọ iwe tan, ti nwọn nlọ ji iwe idanwo ti nwọn fi dan wọn wo gbe.

A gbọ wipe ọrọ aferu gba ibukun yi kiṣe ọ r ọ awọn ọmọ ile ẹkọ nikan; awọn kan ni imọ awọn obi wọn wa nibẹ pẹlu awọn tisa olukọ ti o nkọ wọn nitoripe gbogbo awọn iya ati baba ni nwọn nfẹ ki awọn ọmọ wọn yege ki nwọn ba le ri iṣẹ rere wọ.

O dara bẹ! Ṣe nigbati a ṣẹṣẹ ti ẹsẹ kan bodo ti ọni han an, kinni a ro wipe a tun le ba ninu odo na ? Nigbati o jẹ wipe pẹlu iwa aiṣe otitọ, iwa ẹru ni a fi wọ iṣẹ, kinnise ti a o de ibẹ tan ti a ko ni ma yi iwe pade ti a ko ni ma gba owo-ẹhin.

Ẹnyin obi idi rẹ niyi o ti gbogbo awọn ọdọmọde ti nwọn ṣẹṣẹ jade ile ẹkọ fi ndi ẹlẹwọn kakiri ilu,

Ẹnyin olukọ paapa ọrọ na wa kan yin! gbogbo awọn ọmọ ti nwọn nran wa si ile ẹkọ y i n, ki ẹ tun ori wọn ṣe, ki ẹ fi ọna rere ti nwọn ni lati gba ninu aiye bi awọn ti ṣe le m ọ ẹ r u lati di fun irjuajo wọn laiye ni nwọn ran wọn wa si ile ẹkọ fun, sugbọn ọna ti ẹ nto wọn si ko tọna rara.

A gbo wipe ọpọlọpọ ẹnyin olukọ ni ẹ mba awọn ọmọ ile ẹkọ yi wa ẹna ti nwọn yio fi ri iwe idanwo eleru gba ki ọjọ idanwo p a a p a to de. Ti ẹ ko ba mọ ẹ jẹki a sọ fun yin wipe nkan ti ẹnṣe ko dara rara, kunmọ ati ogulutu ni ẹ fi nfọ awọn ọmọ akẹkọ yi lori.

A tun gbọ wipe ki ẹ ba l e g b a iyi lọdọ Ijọba wipe ẹnyin ni ẹ mọ enia lati kọ daradara ni ẹ se nse eyi. Iwa afi eru gba ibukun ni eleyi kisi jẹki orilẹ ede dide.

# Iwe Si Olotu

# Eleyi Na To Ro Nitoto

Olotu, mo gba fun ọrọ ṣiri ti e sọ fun awa ọmọ Yoruba nipa iwe k a n ti ẹnikan ti o pe a r a rẹ ni Alheri ọmọ Hau a kọ si y i n laipẹyi lori ọrọ ẹgbẹ ọmọ Yoruba ti awọn kan ni awọn fẹ da sile ki irẹpọ le wa larin awọn yoruba.

Ọlọrun jẹki a gbọ, ki a le ni irẹpọ larin ara wa, sugbọn kinise ti inu ma r bi awọn ọmọ ẹgbẹ Ibo nigbakugba ti nwọn ba ti gbọ wipe awa Yoruba fẹ parapọ.

Mo ṣe akiyesi wipe awọn Hausa kiṣe ilara wa rara, a fi awọn Ibo yi. Nkan ti o jẹki nsoro yi ni ọrọ kan ti a gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ Ibo sọ wipe ki a niran ọdun 1948 ti awọn ra ada lori awọn ọmọ Ẹgbẹ Oduduwa t i nwọn fẹ k i awọn ọmọ Yoruba parapọ Iyẹn ni wipe oju ko t i wọn rara nipa ọrọ alada yi ? Bi awọn Ibo yi ba fẹ ki a jọ maṣe nkan pọ, o yẹ ki inu wọn ma dun sọrọ awa Yoruba ti a ba fẹ dapọ Tani a ri bawi bikose awa Yoruba ti ole ati ọkanjuwa ko jẹ ki a fẹran ara wa.

Ẹ ṣe pupọ aye ti ẹ gba mi, ọkọ Ijọba k o ni ṣa yin lẹsẹ.

Emi ni,
Mushin James Babalọla

## O Da Won Loju Nitoto

Mo gba fun awọn baba Onisegun Ita Faji ti nwọn fun gbogbo awọn alaisan ti o lọ sọdọ wọn lati lọ g b a egbogi ọfẹ lọwọ wọn laipe yi. O ni lati jẹ wipe egbogi ti awọn nlo nibẹ da wọn loju nitotọ bi bẹkọ awọn ko ni wipe ki awọn ara Eko wa dan awọn wo.

O ye ki awọn ọkọ iyawo ti iyawo wọn loyun, ti nwọn lọ sun sile dokita Ọba gbaruku ti ile iwosan ibilẹ ti wa yi, ki awọn Nọọsi O b a y e f i wọn ṣe faari.

Bi ẹ ba ri nkan ti oju awọn abiyamọ nri ni ile Iwosan Ijọba ẹ o mọ wipe o yẹ ki a gbaruku ti awọn dokita ibilẹ ti nwọn ba ni egbogi ajẹbina lọwọ. Awọn ara ilu Ghana paapa ni awọn oniṣegun ibilẹ ti nwọn, Ijọba wọn si ran wọn lọwọ pẹlu owo iyebiye

Simpson Street EbutteMetta. Emi ni E. Onifade

## Tani Baba Onitolotolo Ikeja ?

Ẹ jọwọ Olotu, ẹ ba wa bere lọwọ Ayiluka Eleti-Ọfẹ ko tubọ la ọrọ awọn Baba Onitolotolo ti nwọn ko si ọgba ile kan ni Ikẹja ye wa. Awa na mọ ọ r ọ Ayiluka wipe ti ko bo ri ọrọ tan ki sọ ọ.

Nitotọ owo riba ti awọn enia kan npe ni owo ijoko-agba ti ba awọn oṣelu wa ati awọn ọga ibi iṣẹ jẹ patapata. Bi ko ba ṣe bẹ kilo fa a ti awọn kan ni ki awọn Oyinbo onisẹ kan lọ mu ọkẹ k a n o le ẹgbẹdọgbọn pọnun £25,000 ki awọn t o l e g b a wọn laye lati da iṣẹ silẹ fun awọn enia wa ti nwọn ko ri iṣẹ ṣe.

Ẹ jọwọ, olotu ẹ tubọ ma tu aṣiri awọn i r u baba onitolotolo wọnyi jade pẹlu owo riba ti nwọn ngba.

Emi ni
Ọtta A. Akanji

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

### Lati Owo Ayiluka

E Ma Ka
Iwe Irohin
ELETI-OFE
Ti O kun Fun Irohin aladun
Losose

## Awon Elewon Lo Sile Won:

# Ilu Kenya Ati Zanziba Gb'ominira

NAIROBI — Ọpọlọpọ awọn arufin ti nwọn ti mọle lọgba ẹwọn ni inu wọn dun ni owurọ ijẹrin nigbati nwọn ṣi ilẹkun ọgba ẹwọn na s.l; wipe ki awọn na lọ sile awọn darijin wọn fun ominira ti Ijọba Gẹsi fun wọn ni ilu Kenya. A g ọ wipe gbogbo awọn ọdaran ti nwọn da ju silẹ na nlọ bi ẹgbẹdọgbọn enia, ninu 'vọn ni awọn ọmọ ẹgbẹ kan ti nwọn ṣe ibura wipe awọn a gba ilẹ awọn kuro lọwọ ajoji wa awọn ẹdẹgbẹjọ enia ni nwọn tj mọle ninu awọn yẹn,

Ọdọmọdekunrin kan, Karinki Chothara ti o ni enia mejidinlogun ni on pa lorukọ ẹgbẹ Mau Mau ni a gbọ wipe nwọn tun da on na silẹ pẹlu awọn ara ilu rẹ.

Gbogbo orṣirişi enia ni nwọn de si Nairobi tiṣe olu ilu Kenya ati Zanzibar olu ilu Zanzibar lati wa ba wọn ṣe ajọyọ ominira tuntun ti nwọn ṣẹṣẹ gba na, Ọkọ Ọbabinrin ilu Gẹsi, Ọlọla ọmọ Ọba Philip ni o lọ ṣe aṣoju Ọba nibẹ nitori Ọbabinrin paapa ko lọ nitori oyun ti o ni lọwọ nisisiyi.

Ọgbẹni N A Martins, aṣoju Ijọba Nigeria ni Kenya ati Dokita E A Esin minisita kan ninu Ijọba Apapọṣe ni nwọn ran lọ sibi aṣeyẹ ominira na. Alakoso Ijọba ilu Kenya Ọgbẹni Jomo Kenyatta ni o fi iwe pe Ọlọla Adetokunbọ Ademọla pẹlu Lọya H O Davies ti nwọn ba ọkọ ofurufu lọ.

**E ka oro Olotu lori Awon Afi Eru Gba Ibukun loju ewe Kerin.**

### AKIYESI

Ẹnikẹni ti o ba nkọwe si Olotu ki o ma kọ yanju, ki o si ma forukọ rẹ si pẹlu alaye ọrọ ti o nkọwe le lori. Ọgbẹni S. Aroworọwọn, a ri iwe rẹ gba, ọrọ yin ko ye wa rara.

— Olotu

MERCEDES - BENZ

*Vehicles are Built to last, to give many years, and many miles of trouble-free, economical Service.*

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.
LAGOS, APAPA, IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA.
*Sub-Distributors:—*
ARMELS TRANSPORT LTD.
BENIN-CITY . ONITSHA . ABA.

# Awon Kansilo Wa Ninu Ija Ni Ilu Isehin

ISEYIN — Kotofo - kotofo fila Imale ¡ku fefefe ni oro ija ati wahala kan ti o be sile larin awon kansilo afidihe ti nwon yan larin awon omo egbe Alakuko dipo awon omo egbe Olope (AG) ti nwon ti ndari ero ibile ilu Iseyin fun odun gbooro.

Akowe Onirohin wa ni ko si nkan ti o fa ija na ju iwa emi-ni-nao-ni e lo, sugbon awon odo omodekunrin ati obinrin ilu ni awon ko fe iwa ireje ti awon kan fe gbe jade nipa ere na.

Awon Sorosoro kan ri oro Ogbeni Kasumu Owonikoko, alaga Kansulu na ri lo da ija sile; a gbo wipe nigbati ko si nile ni nwon yan alaga miran lehin re, oruko alaga ti nwon yan nje Raji Adabo sugbon ehin Ogbeni Kasumu Owonikoko ni awon egbe odomode ilu Iseyin patapata.

Olola Oyerokun sa relo si Isehin lati lo ba won pari ija na sugbon gbogbo re ko ti bo si. Alhaji Adeleke (omo egbe Afenifere ti nse alaga ile igbimo na ri ki nwon to tuka, ti oide si oro na pe ki ilu le tore,

# Awon Loya Kekere Ko Ilewe Sile Patapata

EKO-Gbogbo awon loya kekeke ti nwon sese ti ilu Oyinbo de, ti nwon wo ilewe ti Ijoba ko fun won wipe nwon ni lati se osu meta gbako nibe ki nwon tun ise ise loya ko ki n w o n to ma gba ise se ni nwon fi aake kori lana wipe awon ko ko eko mo, ti nwon si binu fi ilewe na sile.

Nwon ko lati ro ejo fun Ayiluka EletiOfe awon oniwe irohin mira ti nwon sare lo si ilewe won na ni popo Igbosere lati g b o nkan ti o fa idi re ti nwon fi ko ilewe na sile.

Awon l o y a tuntun na tile j a e r o igbaworan (Camera) gba lowo awon agbaworan oni w e irohin ati ti Ijoba ti n w o n fe gba aworan w on nigbati nwon mbinu kuro n i n u iwe na Ogbeni Odesanya tise akowe egbe awon loya be w o n titi sugbon nwon ko gba oro ti o mba won so.

A gbo wipe idanwo ti Ijoba ni awon ma se fun w o n ni o fa wahala na. Awon loya wonyi ni awon ko fe idanwo a se tun se, nwon ni awon ti se ikan nilu Oyinba kinni o tun fe tile yi.

## Awon Ara Ipinle Mid-West Tuntun Nja Lori Idibo

WARRI — Loru ana, a gbo wipe o to enia mewa ni agbede meji Ijoba Ipinle Iwe Orun ti nwon sese da sile ti nwon fi ara gbogbe nibiti nwon gbe ti npolowo idibo larin awon omo egbe oselu NCNC ati NPC (egbe olomi ni abule kan leti Sapele.

Ni Satide ola yi ni nwon yio dibo lati yan enia Oloye O. Oweh ti Ijoba yan ni asoju lo si ilu Guinea laipe yi, awon egbe oselu meji, egbe NCNC ati NPC ni nwon yan enia sita wipe ki nwon dibo fuu won;

Olola Dennis Osadebay tise Olotu Ijoba afidihe ti nwon da sile ni agbede meji Mid West ni awon kan ngbere lati pa on, lori oro Ijoba Mid West ti nwon se se da sile na. Olotu afidihe na ni on gbo wipe awon ara ilu on ni nwon ndite lati pa on na

# Eleti-Ofe D'araba



### Britain Backs Jamaica:

# On 'Human Rights Year' Move

NEW YORK..... A Jamaican resolution, which would have the General Assembly designate the year 1968 as International Year for Human Rights, receiued whole-hearted support from British delegate, Mr. Patrick Attiee, when it was introduced into the General Assembly's Social, Humanitarian and Cultural Committee.

It was, agreed Mr. Attlee, desirable to begin work on this project at once.

The year 1968 will be twentieth aniversary of the adoption of the Universal Declaration of Human Rights, and the resolution was passed unanimously by the Committee on the eve of Human Rights Day (December 10).

The resolution, which sixteen other nations joined Jamaica in co-sponsoring, requests the U N. Economic and Social Council (ECOSOC) to invite the Commission on Human Rights to prepare, in conjuction with the U N Secretary-General, a programme of activities by member states and the U. N. Specialised Agencies in celebration of this twentieth anniversary and to prepare a list of goals to be achived not later than the end of 1968.

It also invites member states to intensify their domestic efforts in the field of human rights in preparation for an international review of these to be held in 1968.

## Britain Buys More Nigerian Lemons

LONDON - Britain has been buying more Nigerian lemons this year. According to figures just published in "Fruit Intelligence" a monthly Journal circulated by the Commonwealth Economic Committie in London.

Between January and September last year Britain bought 517 cwt. of Nigerian lemons. This year the figure was more than double - 1192 cwt.

Another increase for Nigeria is noted under the heading "other fruit"-this excludes citrust fruit and bananas as well as money stone fruits. The figure given for the first nine months of 1962 as British imports from Nigeria is 1091 cwt. in the same period this year it rose to 3188 cwt.

But Nigeria has been sending fewer grapefruit - 828 cwt. in the first nine months of last year campare with 460 cwt. in the same period this year.

And there has also been a slight drop in the quantities of canned grapefruit Nigeria has been sending to Britain - from 1,695 cwt. in the first nine months of lastyear to 1,009 cwt. in the same period this year.

## Nigerian Cadets On Parade At Dartmouth

LONDON - Two young Nigerians will be among the cadets taking part in the passing out parade at the Britannia Royal Naval College, Dartmouth next Monday, December 16.

They are Joseph Acka and Peter Hemben, both of whom live at Gboko.

The parade marks the end of the term at the College. A total of 569 officers under training will be taking part.

After leaving the College, Midshipmen Acka and Hemben will serve for fiften months aboard British naval vessels to gaing practical exprience of life in navy at sea.

## Invisible Xmas Guests To Aid The Hungry

LONDON—There will be an 'invisible guest' at the dinner tables of thousands of British families this Christmas, as the result of a 'Freedom-from-Hunger' fund-raising campaign which was launched in London last Tuesday, by Queen Elizabeth the Queen Mother.

The Fund's United Kingdom Committee is asking families all over Britain to set an extra place at their Christmas dinner table and to send the cost of the extra meal to boost the funds.

The Queen Mother spoke of the tragic human problem—'more than half the people of the world in dire proverty and hungry' - before receiving a cheque from a cinema appeal which raised almost £30,000.

She also accepted cheques from housewives, including Lady Douglas—Home, wife of the Prime Minister.

## British Bank Forms Partership In Nigeria

LONDON — The London merchant bankers, Philip Hill, Higginson, Erlanger, have finalised arrangements for a partnership in Nigeria with two leading continental banks.

They are the Credit Lyonnais of France, and Italy's Banca Commerciale Italiana. Each is taking a 30 per cent interest in Philip Hill (Nigeria), formed three years ago.

Philip Hill, Higginson Erlanger will retain the remaining 40 per cent. One of the bank's directors Mr J R Colville, is Chairman of the Nigerian company.

This new arrangement should help channel funds from Europe into Nigeria for development," Mr. Colville told our correspondent on Monday Dec. 9.

The two banks who have joined us are among the most important in their own countries and should bring consiqerable benifit to Nigeria. This arrangement will help in the creation of a stronge money market in Lagos, he added.

Philip Hill (Nigeria), specialises in providing acceptance credits and new issue facilities.


# Read

## And Advertise In the Eleti-Ofe

a Weekly Newspaper.

**Ayiluka Ni:**

# Nana Oloye Ni Adajo Akufo Addo

(O bere loju ewe keji)

Awọn Nana Oloye ilu Aganyin ni on na ma nṣe iṣẹ fun nigbati o wa ni lọya. Ti o ba ri Akufo Addo wa sebi o ri Oloye Ladi Moore, nwọn jọ ara wọn pupọ. Lọjọ kanna ni awọn meje gboye lọya ni ilu Oyinbo, ọkọ kanna ni nwọn wọ wa si ile lati London. Ṣe ẹnyin na wa ri 'wipe IWAJỌWA ni jẹ ỌRẸJỌRẸ. Ọlọla Korsah, ẹ ku agba !

## Awon Eketunde

Ọrọ Ọgbẹni TOS Benson ati Ọgbẹni RBK (Arubike) Okafor awọn akukọ nla ti o wa ninu ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) su mi nipa oko-ọrọ ti nwọn nju si ara wọn lori ọrọ ilu pẹlu awọn lebira ebute Apapa ati Pọta (Port-Harcourt) ti nwọn fẹ daduro. Mọ gbọ wipe Okafor ni Benson nṣe ekewọn ọmọ Ibọ ti awọn jẹ alakukọ fun BALE-WA Ọlọla Tafawa Balewa wipe ẹgbẹna titan, aporo ni oku ti awọn ọmọ ẹgbẹ njẹ.

Ẹ tilẹ duro na, oju ko tilẹ nti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ni? Ojojumọ ni nwọn ma mbu ara wọn ninu ẹrọ redio ati iwe irohin. Nko ba wọn wi, Akukọ adiẹ fẹran ki o ma pa ariwo ti o ba fẹ paa. Mo gbedi fun Ọgbẹni Jaja Wachuku, minisita alamojuto ọrọ ilu okere, en tilẹ sinmi ọrọ sisọ nitirẹ diẹ, Ọgbẹni Okafor ni o ṣẹṣẹ jẹ Oloye Abẹnugbọrọ ti ọrọ-sisọ tun kan nisisiyi. Ki a sọrọ si ibiti ọrọ gbe wa, Ọgbẹni Benson paapa fi igbakan ba wọn joye Awoko oloriẹiye ninu Ẹgbẹ Alakukọ na, ṣugbọn ki a mase ba a wi, iṣẹ AKEDE IJỌBA ni o gba, o si ni lati ṣe e.

## Awon Alaso Ereko

Mo ro wipe nkan gba ara wọn fun awọn obinrin alaṣọ oju Gọta Ereko lọdun ni, nitoripe nko ri ki nwọn pa ẹran agbo ṣe saara bi ti ọdun esin ti nwọn pe gbogbo awọn Lemọmu Mọsalasi kọkan wipe ki nwọn ba awọn kewu si igun mẹrẹrin Ereko. Awọn bi Iyaafin Amuda Grillo (AG) Sidi Arose, Muni Balogun ("Wundia Ọfin"), Abibatu Oshodi (Iya Kari) ati Jarin Fakọsi ti mba bi nidi ọrọ na ni nko ba ni iso, nwọn ni gbogbo wọn lọ si Mọsalasi Jimọ ni ọsan ana. Gbogbo awọn yoku, awọn bi Iyaafin Mẹdina Bello (Iya Muri), Iya Fredi, Iya Muyi (ọmọ Lemọmu Ashafa Tijani ati Abẹni Eko ti mo ri, nṣe ni awọn ero kun iwaju wọn, ti nwọn nfi ọwọ gbo'wo lọtun losi.

Bi ọdun Keresimesi yi ba dara fun ẹnyin obinrin alaṣọ Ereko ki ẹ rẹnti emi Ayiluka, ki ẹ fi aṣọ fila ọdun ju mi lori.

## Awon Baba Abiye

Emi Ayiluka mọ Iya-afin Oyinbo obinrin abọlọmọbimọ kan ti a npe ni IYA ABIYE ni ilewosan Adeọyọ ni Ibadan. Nko mọ orukọ suna ti mo le fun awọn onisegun ibilẹ ti nwọn ṣẹṣẹ de ọja Ita Faji l'Eko ju Awọn BABA ABIYE ilu Eko lọ, ki a tilẹ fi ọrọ awọn ọkunrin ati obinrin ti ara wọn ko ya silẹ, gbogbo awọn aboyun Eko mọ Ebute-Mẹtta ni nwọn sọ ti mọ ọwọ awọn onisegun ibilẹ na.

Ẹnikan tilẹ ji ọrọ ofofo kan sọ fun mi ni ile alamojuto eto ilera ti Ijọba wipe Dokita Koye Majẹkodunmi, Minisita alamojuto eto ilera paapa mbọ wa wo eto wọn ninu ile iwosan ibilẹ tuntun na, irin ajo lori ọrọ Ẹgbẹ ọmọ Yoruba ni o si ndi i lọwọ. Ọrọ ni ẹ gbọ yi o, ẹnyin BABA ABIYE, Ọgbẹni L.A. Adeṣbẹgun (Baba Ita Faji) pẹlu Dokita Z.O Salimon ati awọn Ọba-bi-Ọlọrunkosi Anigilaje ati awọn Afolabi Dawodu, Olorukọ nla. Mo tilẹ tun gbọ ti Olotu Eleti-Ofe nfi ọrọ jomitoro ọrọ loju mi nipa ọkọ iyawo kan ti nfẹ mu aya rẹ wa sọdọ yin ti o mbere boya Egbogi yin ko ni osuwọn bi ti awọn Oloyinbo. Mo ni boya ko mọ wipe Aiye ti la jara wọn, awọn onisegun ibilẹ ilu wa gbogbo ni wọn ti fi eto to gbogbo alamọri wọn. Ki ọkọ iyawo na tete mu iyawo rẹ lọ, tabi o nduro de ọjọ ti nwọn yio gba ogun ọfẹ ni ? Gbamu ko tan iba o.

## Egbe Yoruba Parapo

Ẹ jọwọ ẹ jẹki nfi awọn ọrẹ mi, awọn Olotu Ẹgbẹ ọmọ Yoruba ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ, ti nwọn nlo si irin ajo ile Yoruba wipe alọ a dara, abọ a sunwọn awọn Dokita Akerele ati Dokita Majẹkodunmi pẹlu Ọgbẹni S.A Lana ni mo mba wi. Awọn agbalagba Yoruba ni ki a ma ṣeṣe ọrọ na ni bi enikan ba nti oko-were bọ, ẹlomran a ma ṣeṣẹ lọ. Ki a ba awọn agba Yoruba sọrọ ẹgbẹ tuntun na ki o kunna, ṣugbọn emi Ayiluka mọ wipe lati ile ni a ti nko ẹṣọ lọ sode.

Ọrọ pẹ ninu ọrọ Lọya Ọgbẹni G B A Akinjide ti o sọ wipe o da bi ẹni wipe ẹnia kan ni o ṣẹṣẹ tun fẹ sọ ara wọn di orisa fun awọn Yoruba lati ma kẹ. O dara, ẹ jẹ ki a sọ orukọ ẹgbẹ tuntun na ni KASIMAWO. Boya awọn Olotu ẹgbẹ na le tun iwa awa Yoruba ṣe.

## Oku Kan Jinde Ninu Posi Re

( O bere loju ewe kinni )

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ nipa oku arabinrin na, amodi kan ni o nṣe e ti nwọn fi gbe e lọ si ile alaisan na, nwọn ni ko ju ọjọ kẹta lọ ti obinrin na de ile iwosan na ni o jalaisi, nwọn si kesi awọn enia ile wọn wipe, ki nwọn wa gbe oku rẹ.

Awọn enia na si gbe okuna fun awọn alabasinku kan wipe ki nwọn ba wọn ṣe ọlọjọ ọrẹ, nibiti nwọn gbe ti nwọ aṣọ fun oku arabinrin na ni o taji.






Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370; Editor; (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosoko Street, Lagos, P O Box 467